**Lakaye Oro**

Asure tete yio ma mi hele-hele. E n i t i ko ba pele-pele gun esin, yio gun eyiti ko ni ijanu. Nigbara ti o ba gbe si, o di ile agbako.

Şora re ki o to se Onigbowo. Ronuwo ki o to duro fun enia, oni ruru ore lo mbe laiye, ki oro loro ma ba di tire. Aiye Akamara laiye da.

# IROHIN IMOLẸ

MOTTO: IMOLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Wanted**

Advance and apprentice Printers apply in person to the Manager Ire-de Printing Works.

10, Church Street Opposite St. Jude's Church Ebute-Mẹtta

VOL. V No. 303 MONDAY OCTOBER 16 — OCTOBER 22 1961 KỌBỌ MEJI (2d)

# Obinrin kan nrọbi lati bi Ọmọ Abami, yala ọmọ olori meji ni, tabi ẹlẹsẹ mẹrin

IBADAN:– IROHIN KAN WA WIPE OBINRIN HAUSA KAN NRỌBI LATI BI ỌMỌ ABAMI, EYITI AWỌN DỌKITA TI FI AWỌ WO INU OBINRIN NA, KI NWỌN TO MỌ PE ỌMỌ ABAMI NI.

Nişişiyi obinrin na ti bẹrẹ si fun oju pọ lati bi awọn ọmọ abami wọnyi, nitoripe ki obinrin na ma ku si Ijọba lọrun, nwọn gbe obinrin na sinu ọkọ ofurufu lọ si University Hospital, nitoripe ko si ọna rẹ ti nwọn ko fi ni şe işẹ fun ki o to le bi ọmọ na. A gbọ wipe ara Bauchi ni obinrin na, bi obinrin na ba le ru u re, ti o si sọ ọ re eyi ni yio di igba ẹkẹta ti nwọn mbi iru ọmọ abami bayi (Wari-boko).

Alakọkọ rẹ ni, ọmọ olori meji ti nwọn ni agbẹdu kan ti nwọn gbe lọ si ilu Oyinbo lọ şişẹ fun, şugbọn ọkan şalaisi ninu awọn abami na, ekeji rẹ şi mbẹ ni alafia. Ekeji ninu ọmọ Abami ti nwọn bi nilẹ Naijiria ni eyiti nwọn bi ni Okirika ni Ipinlẹ Ila-Orun, Dọkita enia dudu kan lo pin awọn ọmọ olori meji na si ọtọtọ. Iya ti o bi awọn ọmọ abami mejeji ti a da orukọ wọn si oke yi, ekini ati ekeji wọn jẹ ara Ilu Okirika.

Şugbọn eyi ẹkẹta yi jẹ ara Bauchi ni ile Hausa, lọwọ gbeya-gbeya, ati Babarinsa ọmọ Oluwa rere gba wa. Ki Ọlọrun jẹki obinrin na ru u re, ki o si sọ ọ re. Amin.

## Owo Olopa te awon Okunrin meji to fe se Owo aiyederu

GBỌGAN:– Ọwọ Ọlọpa tẹ ọkunrin Onişegun kan ti a gbọ wipe o şe owo aiyederu ti orukọ rẹ njẹ Sanusi Oni nilu Gbọngan ati Ọgbẹni kan ti o njẹ Karimu Akanji ti o nşişẹ aranşọta nilu Modakẹkẹ.

Ẹsun ti nwọn fi sun awọn Ọdaran mejeji na nipe nwọn şe owo aiyederu (counterfeit notes) nwọn si tun ka irinşẹ rẹ mọ wọn lọwọ. Nwọn ri owo Kọrẹnsi o ni Pọnun kọkan mẹtaleladọjọ ati oni şile mẹwa-mẹwa mẹrin lọwọ wọn. Nigbati irohin gbojikan pe, ole nja pupọ ju, Ọlọpa Ibilẹ mẹrin parada, ninu wọn ni James Adeagbo, bi wọn ti nlọ ni wọn şe kongẹ Sanusi Oni, nwọn bere lọwọ rẹ pe, nibo ni o nlọ, o si dahun pe, Onişegun ni on nşe, bi ko ba si da awọn Ọlọpa wọnyi loju ki wọn tẹle on kalọ sile.

Nigbati wọn de ile rẹ, o fi orişirişi egbogi ti o ti şe lọjọ pipẹ sẹhin han wọn, bi ado, ato, ọsẹ, Şigidi, agunmu ọpa ati nkan bẹbẹ. Bi o ti nfi awọn nkan wọnyi han awọn Ọlọpa, o wa fẹ ju apo ti o gbe kọ si ẹhinkule na, ibẹ ni awọn Ọlọpa ni irọ! ki o bẹrẹ gbe, nigbati wọn tu apo na wo, wọn ba owo aiyederu nibẹ, ẹjọ na ko nşe kekere, adajọ wa yẹ ẹjọ na si igba-miran.

## Okunrin kan fe fi tulasi wole lo ba Alhaji Tafawa Balewa



EKO:– A ko mọ ohun ti o ko si Ọkunrin kan ti o njẹ Lasibi Harri lori, ti o si sọ fun Ọlọpa ti o nsọ ile Alhaji Tafa Balewa pe ki o jẹki on wọle lati lọ ba Balewa sọrọ kan, Ọlọpa na kọ, Ọkunrin na si nfẹ fi tulasi kayandoro wọ ile.

Ibẹ ni on pẹlu Ọlọpa na ti wọ iya ija, Ọlọpa meji lo mu on nikan, Ọkunrin na ni a nwo ninu aworan yi ti o nrẹrin bi Ọlọpa ti nfa lọ si Itimọle.

# Ọrọ Olotu

## Imoran fun awon Onikeke ologere (Cycle) ati awon Onimoto

Lọwọ Iku gbigbona ati Iku ojiji, Oluwa rere gba wa o, ma ṣe jẹki a rin ni ọjọ ti ebi yio pa ọna o. A m i n. Ẹnyin ara, Imọran ti awa Oniwe Irohin Imọlẹ fẹ fun nyin yi, ti ẹ ba le tẹle yio dara pupọ, nitoripe ẹmi wa ko pe meji.

Lọna kini yio dara f u n gbogbo wa lọpọlọpọ bi a ba fẹ lọ sibi iṣẹ tabi ode, ki a tete ma jade nile, nitoripe ikanju pẹlu iyara-gaga ọkan na ni wọn, o fẹrẹ jẹ ikanju ati amọju lo ma nfa Iku ojiji fun Onikẹkẹ ologere, eyi ko tọ r a r a, ohun ti o tọ ti o si yẹ nipe, ki ọmọ enia sa asala fun ẹmi rẹ. A fẹ ki a ṣe akiyesi lati ọdọ awọn ara oko, ti wọn ba ti gbọ fere mọto, nṣe ni wọn ma sa lọ bi idaji ibusọ kan titi ti mọto na yio fi kọja tan, ṣugbọn amọju tabi fari lo nyọ awa ọmọwe lẹnu, papa on lo nfa Iku ojiji ba wa lode oni.

A ko le kọja lai ko ma ba ẹnyin awa m ọ t o sọrọ (Driver) ni ṣoki, nitoripe ẹmi wa ko pe meji, Oluwa ninu anu rẹ yio ma sọ olukuluku wa o, p u p ọ ninu awọn awa mọto ni ko ni suru to rara, o di igba melo ti a mgbọ wipe awọn Oyinbo kan wa mọto, o lọ fi pa enia, a ko sọ pe ko si rara, ṣugbọn ko pọ gẹgẹ bi ti awa ọmọ Ilẹ Naijiria, ti a mọ ayinike ilẹ wa. ẹ ko ri pe o yẹ ki a kiyesi ara wa gidigidi, Bẹni ki ṣe pe a ko mọ mọto yi wa, ṣugbọn amọju ati karimi lo nyọ wa lẹnu.

Nitorina a bẹ ẹnyin awa mọto wipe ki ẹ ma ni suru, ki ẹ si ma fi l a k a y e ati ọgbọn wa mọto nyin nigba gbogbo, bi ẹ ba nṣe eyi I k u mọto yio ṣe ọwọn fun wa, Bakanna ni awa ti a nfi ẹsẹ wa rin fẹrẹ dabi ẹnipe a ti lẹ ka Iku na si ohun kekere nipa pe, bi jamba ba mbọ lẹhin wa, a o ma sọpe, ṣe nko si lọna mọto, kini mọto yio wa ṣe lọdọ mi, ẹpa npa ara rẹ, oni on npa Ikun.

Nigbakigba ti a ba ti gbọ fere mọto lẹhin wa, o fẹ duro ni tabi ko fẹ duro, ẹ jẹki a sa asala fun ẹmi wa, nitoripe ẹmi kan ṣoṣo ni a gbe wa sile aiye yi, ti o ba si bọ, o di gbere, o di arinna ko, o di oju ala, o tun di ọjọ ajinde nuni. Lakotan ọrọ wa ti ọsẹ yi, ẹnyin onkawe wa, ẹ ma ṣe jẹki a fi ilaju ti ko tọ ba igbesi aiye wa jẹ o, nigbati irufẹ Ilaju yi ko iti de, iruoriṣiriṣi Iku ojiji bayi ko iti si, ṣugbọn lati igbati Ilaju ti bẹrẹ ni a ti nku Iku airotẹlẹ, a ko le ri ọjọ kan ti mọto ko ni ṣe ni leṣe tabi ko pa enia. Oluwa ninu anu rẹ yio ma sọ wa, ṣugbọn ko si igbati Ọlọrun ko n s ọ wa o.

O wa ku si wa lọwọ, awa papa ni lati sọ a r a wa, ki ẹlẹsẹ ma ṣe fi oju di Onikẹkẹ, ki Onikẹkẹ ma si ṣe fi oju di Onimọto, ti a ba nṣe eleyi Iku ojiji yio jina si wa o. O l u w a Ọba Alanu julọ ki o ma fi isọ rẹ sọ gbogbo wa o. Amin.

## Awon Usise Redio meji ni ilu Oyinbo



Awọn ti ẹ nwo ninu aworan yi ni ọmọ Naijiria ti o nṣiṣẹ fun Redio ni Londọnu orukọ wọn ni Ibrahim Tahir ati R a y Ellington ti o jẹ gbajumọ onilu Ọmọ enia dudu ti o jẹ ara ilẹ Amẹrika. Awọn mejeji nsọrọ Jori ẹrọ Redio ni B. B, C. Londọnu.


## KERE O! AKIYESI PATAKI

Awa na le jẹri wipe ojulowo haunhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS, Awa na nlo ni ilu Gold Coast (A n k a r a) Ghana pẹlu, meji rẹ kosi ninu gbogbo oriṣiriṣi Egbogi kakiri Ilu Naijiria.




## Irohin kakiri Igboro Ilu Eko

Bẹna si ni ẹwọ Igboro Ilu Eko, irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia, tọmọde ti agba ni asiko yi ti wọn si nfi ṣe ọrọ ati orin kọ larin ara wọn jẹ nipa ti Egbogi Jamani olokiki yi ti wọn npe ni Leopills.

Imoran awọn Dọkita Oyinbo ti wọn ṣe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to, ti o jẹ ojulowo giriki ati atamatase fun iwosan JẸDIJẸDI bi o ti wu ki ọjọ rẹ le pẹ to bẹna si ni awọn tun le fi ọwọ sọ aya tabi ṣe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi aisan bi Akọ Inarun. Lakuregbe, Ẹjẹ dudu lara, Arun Ẹdọki, Iju Igbesse, tabi Aikori Igbọnsẹ dede, Inurirun nigbakugba Ara-wiwo, Esanri, Ẹhin didun, Oju sisan tabi Aiko riran kedere Kokoro buruku lara, Osi inu Onigbameji, ati oriṣiriṣi arun miran gbogbo pẹlu "Wipe" wọn yio ri alafia ni kiakia ti awọn ba nlo egbogi "LEOPILLS" nitoripe a si tun ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa ssiọ di ọtun patapata.

ṢE IRANTI PE ALAFIA NI OGUN ORO
IJAFARA SI LEWU PẸLU (POSTAGE 1/9d)

Egbogi Leopills:- Igo nla sile mefa pere ni.
Igo kekere:- Ṣile mẹta abọ pere ni.

Bere ojulowo Egbogi omiran fun oriṣiriṣi amodi ti o ba fẹ ni Ṣobu awọn:-

**Waterloo Medice Stores**
**8, Palm Church Street, P. O. Box 333. Lagos Nigeria Phone: 22878.** ati pẹlu ni Ṣ ọ b u arabinrin Mrs C. O Babajide near Health Office Ibadan ati ni A b i m b ọ la Medicine Stores B29 Okeṣha Street, Ileṣha Bisale Medicine Stores British & Foreig Medicine (Dealer) S. W. 6/458 AGBOJO STREET, IBADAN, N.

AKIYESI:- Ri daju gbangba wipe ṣobu ti wọn nta lo gbe ranṣẹ lọ ra, bi bẹkọ awọn ẹlomiran yio fi ERU lọ ta adamọdi tabi oriṣi omiran fun ọ o, maṣe gba rara.

# Ipade Igbimo Zumratul Hujaj Dun

ỌYỌ:- Ẹgbẹ Zumratu ṣe ipade apapọ kini ni gbọngan Atiba, Ọyọ ni ọjọ aiku tiṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi, labẹ aṣia Ẹgbẹ Ilọsiwaju Musulumi. Ẹ sọ awọn Alhaji lati bi adọta ilu ti o wa ni Ipinlẹ Iwọ orun ni o pe ṣoṣo sibẹ, gbogbo wọn si ṣe ẹṣọ olowo iyebiye.

Lẹhin ti Alhaji A b i ọ l a, Lemọmu agba apomu ti fi adura ṣi Ipade Igbimọ na ni Alhaji Y. K. Apepa Yakub si fi Alhaji Oloye S. A. T. Awẹlẹnjẹ Olori ẹgbẹ Ilọsiwaju Musulumi han pẹlu ọrọ apọnle gẹgẹbi A l a g a.

Oloye na ati O l o y e Alhaji S. O. Gbadamọsi sọ iṣẹ ribiribi ti ẹgbẹ Zumratul Hujaj ati ẹgbẹ Ilọsiwaju Musulmi ti ṣe ati eyiti nwọn si nṣe lọwọ fun anfani gbogbo awọn musulumi. Nwọn si ṣe alaiye yekeyeke pe nwọn ti ṣe nṣe iranwọ fun ẹniti o ba fẹ lọ jọsin fun Ọlọrun ni Mẹkka ati Mẹdina ati ni Jerusalem.

Awọn Alhaji Ọlọla Tafawa Balewa, Alakoso apapọ Ijọba Ilẹ Naijiria, Ọlọla Adesọji Aderẹmi, Gomina Ijọba Iwọ Ọrun ati Alhaji Dọkita Sadrudeen O. Biobaku, si fi iwe ranṣẹ si Igbimọ na, Nwọn si kansara si ẹgbẹ Ilọsiwaju Musulumi ati ẹgbẹ Zumratul Hujaj, nwọn si ki wọn ku orire.

Ki nwọn to mu Ipade na de opin nwọn lọ ki alaiyeluwa Ọlọla Bello Gbadegẹshin, A l a fi n Ọyọ, o si fi orişirişi onjẹ ṣe wọn lalejo o si fi ẹbun nla kan ta wọn lọrẹ. Diẹ ti aye wa fun lati ṣdarukọ ninu awọn enia pataki-pataki ti o pe sibẹ ni Alhadji Oloye Ṣhittu Balogun, Alhadji Ajijọla Anọbi, Alhadji S. B a l o g u n, Alhadji Leyẹn ati Alhadji Arikewuyọ.

# Awon Igbimo egbe Gbogbo Agbaiye lo be ilu Edinboro wo



Awọn enia dudu meji ti o mbẹ ni apa osi aworan yi ni, awọn meji ninu ara awọn Igbimọ ilẹ Naijiria ti wọn lọ si Igbimọ ẹgbẹ gbogbo agbaiye (Commonwealth) orukọ wọn ni, Ọgbẹni B. O. Ikeh M. P. ẹni keji ni Alhaji Isa Kaita ti iṣe ọkan ninu awọn minister Oke-Ọya.

Awọn ni a nwo nigbati nwọn lọ ṣe abẹwo afin Edinbọrọ (Edinburgh) wo ni ibiti ọkọ Ọba obinrin Gẹsi ngbe Ṣọja ti a nwo ni ọwọ osi ni ẹniti o nṣọ ile ọkọ ọba na On ni alejọ yio kọkọ kan ki nwọn nwọn to wọ ọgba afin Edinbọrọ.


# Owo eni lafi tun iwa eni se

Bi silowolọwọ ba nda ọ lamu, bi airọmọbi mba ọ lọkan jẹ, tabi airiṣẹṣe lo nyọọ lẹnu, tabi o tilẹ nşiṣẹ na owo iṣẹ na ko duro lọwọ rẹ. Tabi awọn Ọmọraiye ko jẹ ki o gbadun igbesi aiyẹ rẹ ni gbogbo ọna kona.

Ọkọ rere tabi aya rere lo njẹ ọ niya. Tabi amubọ ọkọ tabi ti aya, tabi ọja ti o nta ko lọ dede, tabi ohun miran lo mba ọ lọkan jẹ ni gbogbo ọjọ.

Mọ daju wipe dịẹdịẹ lo kọko bẹrẹ. Ki o si tun ẹna rẹ ṣe. Kọwe pẹlu Şile Mẹwa abọ (10/6) pẹlu Sitampu oni tọrọ (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunṣe adanwo na lọdọ:-

AWORAWỌ
16, MỌLẸYẸ STREET
P. O. BOX 166 YABA - NIGERIA



BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TỌNIKI TITUN TI O ṢẸṢẸ DE TI WỌN NPE NI:-

"DYNAMI REN" TONIKI

EGBOGI AJẸBIDAN FUN AGBALAGBA ỌKUNRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awọn Jamani ti nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ. Lẹhin igbana a ko ri irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju bẹ yẹn mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ranṣẹ si awọn Ogbologbo Dọkita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye. Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ atipe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu. Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Onibara wa mọ daju wipe kosi aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Ẹgbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi kọ. Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣe ṣiṣe ti o ko ba le jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de okọn lọsan tabi loru, bi awọn "Iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara to E-emi (breath) inu ko ba gunlẹ da radara to nitoripe arẹ tabi wahala ṣiṣe ko "NJẸ" fun awọn ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun lọ si oke de adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di Ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kọnkọn nigbakugba "Arẹ" nigbakugba yio salọ patapata pẹlu.

Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

ADEDUN CHEMIST
4, WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.
ADEBỌGUN PATENT MEDICINE STORES.
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN

## Bi o ti ndun Eiye Be ni ondun Enia.

LATI OWO:— LATIFU A. BABALOLA
Oludasile ati Akowe Agba Egbe Imole Aiye

Iwo ore mi, iwo ni mo mba soro ‹tata yi nitoripe, afi ogbon ologbon se ogbon lo nje ologbon afi ero elero se ero lo nje Omero. Sugbon iwo ore mi iberu Oluwa ni Ipilese ogbon. Bi o ba nro ohun rere kan fun ara re, ranti ti omo enikeji re ri e n i a loju, ti owo ko kan nitoripe ara enia ni ise wa. E mase da Eranko ati Eiye loro, nitoripe bi a ba fi pepe gun eiye ti osi ke, ti iwo si rope, iwo nse, ohun g u n m o, ranti wipe bi oti ndun omo eiye ti o fi nke iwo si yo nitoripe iwo ko gbo ohun eiye ni s g b o y e fi oro na ro ara re iwo wipe, bi a ba fi irufe pepe be gun iwo paapa nje iwo je kasi ohun rere bi? Bi aba ngegi ninu Igbo o ye ki a mase fi oro ro ara eni wo. Ko si eni meji fun wa laiye ayafi Olorun Eleda nigbati ose eda enia tan, o fi Emi si ninu, o ni ki o ma wa laiye, e beru Olorun na, Oba ti ko l'abosi ni.

Ki a joko, tabi ki a dake jeje, ka mase ikilo fun enia buruku pe iwa re ko dara, ka ri eniti nmidara ki a mase sayi si Oluware, nu iwa yi dara baun, ro ki o to se. Lose to mbo lagbara edumare e o ma gbadun wi.

Read The IROHIN IMOLE every week. It is a Yoruba Weekly Paper that will provide you with more News more Pictures and more Fun. It will enlighten, entertain and inform you. Always read:-

"Irohin Imole"

The most exciting controversial Yoruba weekly Paper

## Idile Oba Gesi Oko Elisabeti II



Eniti a nwo ninu aworan yi ni okan ninu awon ebi oba ile Gesi, on ni oko oba Obinrin Gesi ti oruko re nje Prince Phillip tabi Duke of Edinburgh aso ti o wo yi ni a s o ti Ogagun ile Kanada pelu amure Omogbo.

Abi nilu Kotiu lojo keje Osu June ni Odun 1921, o je omo idile oba ile Griki o si tun je ibatan O g a g u n. kan ti nwon npe ni Mountbatten nigba ogun.

Nilu Gesi ni omo oba Phillp gbe ti kowe, nibe losi ti npete lati ko ise ologun ti oju omi.

şile kan perẹ ra pakẹti 'ASPRO' TITUN yi




Pakẹti "ASPRO" titun yi wa fun tita nisisiyi nibikibi. Sile kan pere ni owo rira rẹ, kore ẹgbogi "ASPRO" mejila ni owa ninu rẹ. Nisisiyi, ẹnikẹni le ni "ASPRO" ni ipamọ sowẹ lati ma a lo o ni gbara ti o ba ti ni OTUTU-IBA. O ko le mọ igbati OTUTU-IBA yio kolu ọ tabi ẹbi rẹ. Mura sile.
Ra pakẹti "ASPRO" titun oni şile kan lasiti

'ASPRO' nda irora
OTUTU-IBA DURO

# IGBESI AIYE MI NINU IGBO AILOPIN (APA 5)

Lati Owọ:- Simeon Adegoke Fatoki

Ṣugbọn ti o ba seti esu,' a ma ba ona rẹ lọ, nigbati o de ọdọ mi, o kọkọ bi mi lere o ni iwọ ọmọ enia, ti eṣu ni iwọ nṣe ni abi ti Ọlọrun? mo kọkọ duro nko da lohun, o si ke mọ mi bi gbati ara san, o ni iwọ ko gbọ ohun ti mo nba ọ sọ ni, abi iwọ ko mọ ẹniti ẹmi iṣe ni ndan? Emi ni aṣoju eṣu ni inu Igbo Ailopin yi, ọjọ pẹ ti mo ti de ibi yi, ẹgbẹrin ọdun ole meji ni emi si ti wa pẹlu awọn ti o ba wa sinu Igbo yi.

Mo ti pa ọpọlọpọ enia ti ko gba ti eṣu gbọ ninu Igbo yi, ẹmẹjila ni emi si ma nlọ si ọdọ eṣu ni ode Ọrun lati lọ fun ni abọ ohun ti mo ba ṣe ninu Igbo Ailopin yi, ti iwọ ko ba gbọ ti eṣu, emi yio kanọ ni kumọ yi pa, ti iwọ ba si gba tirẹ emi yio da ọ si, mo fẹ ki o dami lohun nisisiyi, eyiti iwọ nṣe nibẹ, ti oko ba si le gba kumọ yi asepe emi ati iwọ yio wọ idimu ti emi ba si ti gbe ọ lulẹ iwọ yio ku.

Nigbati aṣoju eṣu pari ọrọ rẹ tan, mo wo, mo si bu si ẹrin mo ni se iwọ ni iranṣẹ eṣu lati ode Ọrun? mo fẹ ki o mọ pe ti Ọlọrun Ọba ni emi iṣe, emi ki ṣe ti eṣu rara, awọn ẹni ibi ti wọn dabi iwọ gan ni wọn nṣe ti eṣu. Mo ṣe tan lati ba ọ ja, mo si ni ireti pe, lagbara Ọlọrun Ẹlẹda mi, ti ki doju ti ẹda ti o ba nṣe tirẹ, emi yio ṣẹgun rẹ. Ọna ti awọn ọmọ Isirẹli fi ṣẹgun ọmọ Filisitini ni ọjọ kini ni emi yio gba ṣẹgun rẹ gẹgẹ bi awọn ogun Farao ti ṣegbe sinu Okun Pupa, gan ni iwọ yio ṣegbe loni yi. Nigbati mo pari ọrọ mi yi, o wo mi awa mejeji si wọ idimu, aja titi ti ilẹ ọjọ na fi su, nigbati a nja, awọn iwin ati ọrọ wa lati wo wa, gbogbo wọn pe jọ, wọn nwo ẹniti yio pa ẹnikeji rẹ. Ninu awọn ọrọ ati iwin yi ni wọn tan ina si wa ti asi nja ni arin oru, Iwọ Onikawe irohin yi, ija yi pọ ti o jẹ wipe aiye gbọ ọrun mọ, mo gbe ki nfi ẹhin rẹ lelẹ ṣugbọn irọ ni ko sese, on na gbe mi ki o fi ẹhin na okuta, bakanna ni ko sese, mo sa gbogbo ipa mi asan ni gbogbo rẹ jẹ.

Nigbati o ti di ọjọ kẹta ti a ti nja ni mo ba bẹrẹsi ke pe Ọlọrun Ẹlẹda mi kẹlẹkẹlẹ ni inu mi, mo nbẹbẹ ki o ma sai doju ti Iwin yi, mo ni Ọlọrun Ọba ti o da aiye ati ọrun, ẹniti ọta ko le doju kọ, jọwọ ma sai ran ogun ọrun wa ki wọn ran mi lọwọ lati le ṣẹgun ọkunrin yi loni, mo ko kikankikan, Ọlọrun si gbọ adura mi, nigbati o to ọjọ kẹrin ti a ti nja ni mo si gbe lọ sibi itakun kan, nibiyi ni Itakun kọ ni ẹsẹ ti o si subu, bi o ti subu ni o npọka iku ti ko si le dide mọ. Gbogbo awọn ẹranko, Iwin, ati abami ẹda ti o wa nibẹ fi ariwo ta, wọn ni o ṣe ọkunrin alagbara. Inu emi na dun, mo ju ọwọ si wọn, mo ni ki ṣe emi ni mo ṣe Ọlọrun ni.

## Alaiyeluwa Oba Gesi



Ẹniti a nwo aworan rẹ yi ni Alaiyeluwa Ọba Gẹsi Elisabeti Keji, o duro lori ibiti gbogbo enia ti le ri, ẹ o ri o mura, o nlọ si Igbimọ nla.

## Adewunmi di olori Alhaji Egbado

Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọgbọnjọ oṣu kẹsan ọdun yi ni awọn Alhaji, Alfa ati Lemọmu Ilu panupọ yan Alhaji Abudu Salami Adewunmi ni olori gbogbo awọn Alhaji Ilu Ẹgbado ati awọn agbegbe rẹ. Ni Gbọngan spesi "Orona" Ilaro ni wọn pe si yan ni Ilaro wọn, wọn si le ni igba enia Lemọmu agba ni o si ṣe Alaga wọn lọjọ na diẹ ninu awọn Alhaji ti o sọrọ aponle nipa Alhaji Adewunmi sọ pe, ẹlẹsin enia ni olori wọn na, o si jẹ ọloyaya ati Onikokari.

Alhaji Adewunmi si dupe gidigidi lọwọ wọn, o sọ pe, pẹlu ogo Oluwa on yio ma ṣe ẹtọ larin wọn. Nwọn si fi ọjọ ti wọn yio we lawani oye fun si ọjọ karun oṣu kọkanla ọdun yi, wọn si mu ipade na wa si opin pẹlu adura fun Ẹgbe ilọsiwaju Musulumi, Naijiria, ti o ṣe okunfa ẹgbẹ awọn Alhaji Naijiria.


## MOGBAYI COUGH MIXTURE

Mogbayi Cough Mixture jẹ Ogun Ikọ pataki ti a ṣe ni aṣepe lati wo awọn Ikọ oriṣiriṣi san ni kiakia. O dara fun Ikọ agbalagba ati Ikọ ọmọde beni o si tun dara fun Ikọ ọmọ ọwọ pelu.




O dara pupọ ju gbogbo ogun Ikọ yoku lọ. O dara fun awọn arun Ikọ wọnyi, Ikọ ti o ma nha enia ni ohun, Ikọ ti o ma npọn enia loju, Ikọ ti ki jẹ ki enia sun dada, Ikọ ti o ma ndun enia lẹgbẹ, Ikọ ti o ma ota enia ni aya, Ikọ ti o ma nfa Ẹfọri, Ikọ ti o ma nfa arẹ ba ara, Ikọ ti o mu ki enia ma pọ ẹjẹ, ati awọn Aisan miran ti wọn somọ Ikọ bi aiperi, oyi etc.

Mogbayi Cough Mixture yi dara pupọ fun enyin ti Ikọ nyọ lẹnu. Ẹ ma ṣe ṣahun fun alafia ara yin, alafia ni opin ọrọ ijafara ni ewu pupọ, tete lọ ra Igo kan. Mogbayi Cough Mixture, yio wa ni ile itaja Egbogi ti o wa ni adugbo rẹ, Igo kan rẹ jẹ 2/6d' arapọ rẹ jẹ 24/-.)

**LILORE:-**

Ọmọ oṣu mẹta—Idaji ṣibi tea kan ni wakati mẹtamẹta
Ọmọ oṣu mẹta si mejila: Ṣibi tii kan nigba mẹta lojojumọ
Ọmọ ọdun kan si mẹfa:- Ṣibi tii meji nigba mẹta lojumọ
Agbalagba.........Ṣibi Imukọ kan nigba mẹta lojumọ

*Wholesale Distributors:-*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West, Lagos, Nigeria. Phone 22515.

34, Docemo Street, Lagos. Phone 24247.

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Egbe buburu a ma ba iwa rere je

Lati Ọwọ:— EZEKIEL JACOB.
No. 41. ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Inu mi yio dun bi Olotu ba gba mi laye ninu iwe rẹ oloyin mọmọ lati le fi Itan mi yi si awọn ẹlẹgbẹ mi leti, ni ọjọ kan ẹiyẹ yanjayanja kan nfo lati odo kan si ekeji, bi o ti nfo kọja oko kan ti a ṣẹṣẹ gbin agbado si, ori ọpọlọpọ aparo ti wọn njẹ agbado ninu oko na. Yanjayanja ki njẹ agbado rara, ẹja ni o njẹ, eti odo ni o si ngbe, nigbati ẹiyẹ yi ri awọn aparo ti njẹ oko oloko, o fẹ lati ba wọn kẹgbẹ, yanjayanja na ba silẹ o si nyan larin awọn ẹlẹgbẹ rẹ titun, lẹhin ti yanjayanja na ti ba silẹ ni awọn aparo ti gbọiro ẹsẹ Oloko ti o mbọ sinu oko rẹ ọkan ninu awọn aparo kigbe idagiri kẹ, kẹ, kẹ, gbogbo awọn aparo na si tu giri.

Nwọn gbidanwo lati lọ ṣugbọn nwọn ko le lọ ati yanjayanja na pẹlu, nitoripe nwọn ti ko sinu awọn ti Oloko ti dẹ silẹ fun wọn, nigbati Oloko de ti o gbe ada soke yanjayanja bẹ ẹ oni Alagba jọwọ da mi silẹ, ṣe Iwọ na mọ pe odo ni mo ngbe, emi ki si njẹ agbado, ẹja ni onjẹ mi, oloko dahun pe bi o tilẹ jẹ wipe Iwọ ki jẹ agbado, ẹja ni onjẹ rẹ ati pe eti odo ni Iwọ ngbe, nitori mo ba ọ ninu awọn hukohuko yi, emi yio jẹ ọ ni iya, gẹgẹbi ọkan ninu wọn. Pu! ni oloko lu u ni ada lori, o pa birabira ki o to da silẹ.

Njẹ ẹnyin ẹlẹgbẹ mi, ẹ ma ṣe kotu ẹgbẹ buruku, nitoripe ẹgbẹ buburu ama ba Iwa rere jẹ.

## Awon Asoju kakiri aiye lo be Ile ise Agbe Gesi wo



Ninu ipade kan ti Ijọba Gẹsi pe orişirişi awọn Ilu pataki-pataki si, lati wa wo orişirişi Ẹrọ ti nwọn fi nṣe iṣẹ Agbẹ. Ninu aworan ti a nwo yi ni a le ri awọn meji ninu awọn ikọ ti o lọ sibi ipade na, orukọ wọn ni wọnyi, Oyinbo gigun ti o duro lọwọ ọtun ni Ọgbẹni J. M. Munro, on ni olori awọn agbẹ ti o ngbin Owu, ẹniti o duro ni arin meji ni Malam Alikali Bida ati Ọgbẹni I. S. Nkaka olori kan nibi iṣẹ agbẹ ni ilẹ Tangayika.

## Imoran fun Omode Nitori Ehin Ola

Lati Ọwọ:— Adisa Taiwo. No. 24, Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Oju ẹniti o ma la, a ri iyọnu. Ikoko ti yio jẹ ata, idirẹ a gbona. Toto! o ṣe bi owe. Igba mẹta ni igba enia ni aiye yi, Igba owurọ, Igba ọsan ati Igba alẹ.

Lati igbati a ti wa ni Ọmọ ọwọ titi de Igbati asi nkọ ẹkọ ni igba Owurọ, Igba Ọsan ni ti a nṣiṣẹ ti a si di ẹni ti nṣowo Ọmọ. Igba alẹ ni Igba ti adi Arugbo, ti a ko le ṣe iṣẹ agbara kan mọ. Akoko yi ni a nsọ pe enia di Ọmọde igba keji Ki ẹ fi Pẹlẹlẹ ka Itan kekere yi:-

Awọn ọmọde meji kan wa ti wọn jijọ wa ni Kilasi kanna ni Ile iwe. Ọkan njẹ Ajisafẹ ekeji njẹ Nimọta. Ajisafẹ jẹ ọmọ ti ko ni itara si ẹkọ rẹ, afẹ aiye ti kun ọkan rẹ, osi nka 'bawi Olukọ si iwọs ati iya, ṣugbọn Nimọta mọpe a ki nfi oju bọrọ gba ọmọ lọwọ ekurọ, omura lati jẹ orukọ rẹ de'le. Nigbati awọn mejeji ti jijọ wa ni ile ẹkọ, iwe kẹta ni Ajisafẹ ti sakuro ni ile ẹkọ ko le fi ori ti iya iwe kikọ mọ, osa lo si ilu miran. Eko ni nitori oti igbọ pe ile afe ni Ajisafẹ de Eko, o wa mọ pe eko ko dun fun ẹniti ko ni Iṣẹ lọwọ.

## Bi Omode ko gbo Itan agbo Aroba.

1 Tani ẹniti o kọkọ jẹ oye Ọba Eko?
2 Iru awọn alawọ funfun wo lokọkọ de Eko?
3 Tani kọkọ mu Iwe Bibeli wọ Ilu Eko?
4 Tani Alabojuto Alafia Ilu Eko?
5 Darukọ ohun mẹta ti o mọ pe oṣẹlẹ ni Ilu Eko ninu Ọdun 19/60?
6 Ọmọ Ẹgbẹ Kelo ni Naijiria ninu Ẹgbẹ U. N. O.?
7 Kini le awọn Oyinbo Potogi kuro ni Ilẹ Naijiria?
8 Tani kọkọ jẹ Oye Gomina Ilẹ Naijiria?
9 Ọba wo lo jẹ Siwaju Ọba Adele?
10 Ilu wo ni a ti bi Bishop Ajayi Crowther?
11 Ilu na jẹ Gold Coast tẹlẹ ri, ṣugbọn nigbati wọn gba Ominira wọn yi orukọ wọn pada kini wọn npe Ilu na nisisiyi?
12 Kini wọn ti npe Odo to ṣe pataki ni Ghana?
13 Ọdun wo ni wọn da Owo Ẹru duro?
14 Tani ẹniti o da duro?
15 Ninu Ọdun wo ni wọn fi Akintoye Joye Ọba Ilu Eko.

WO IDAHUN AWỌN IBERE WỌNYI NI OJU EWE KEJE.

IWỌN IWE KO ṢE MANI
IWE EGBOGI FUN ONIRURU IWOSAN;
IWE ADURA IṢẸGUN AWỌN AJẸ;
IWE IFA AGBỌN-NIREGUN, IWE ITUMỌ ALA PẸLU IWADI NKAN;
IWE LILO ATI AGBARA PSALMU;
★★★ IWE ADURA TETE DA MI LOHUN:
★★★ IWE ITAN ABALAIYE ATI TI IṢẸDALẸ

KỌWE FUN IWE-ITAJA:-
OLOTU BOX 104
EBUTE METTA, NIGERIA.

## Akoko to fun awon Omo Igbomina lati ronupiwa

Lati Ọwọ:- ỌMỌ AROWOROWỌN

Owe yoruba kan sọ bayi pe, Bi owe, bi owe ni a nlu Ilu Agidigbo, Ọlọgbọn lo njoo ọmọran ni si mọ ọ awọn ọlọgbọn ni iwe yi nbawi, ẹnyin ọmọ Igbomina, akoko to, ejẹki a ni irẹpọ larin ara wa, ki a le bọ kuro, ninu ajaga ẹru ati asingba ọjọ pẹ jọjọ ti a ti nmu ẹnu kan ọrọ yi, ṣugbọn anu ṣe ni lati sọ wipe awọn ọmọ Igbomina ko ya si ọrọ na rara. alalikua, ẹ mọ wipe ki a mase le bọ kuro ninu ajaga Ẹru ni adura awọn ti nwọn nmu wa ṣin lojojumọ, awọn enia na ko ni iṣẹ kan, nwọn ko ni oko tabi odo awa Igbomina ni nwọn njẹ. Bi ojo ko rọ, ti agbado ko si gbo, oju gbogbo wa ni yio ja Ẹnyin ọmọ ile Igbomina eje nṣe ẹjọ nṣe nilẹ wa, gbogbo ayin ri ẹsi dakẹ, njẹ ẹnyin ko mọ pe ẹra ko fẹ poporo deru awọn enia buruku fẹ fi ori ara wa

WO IYOKU NI OJU EWE KEJỌ

EYI NI IDAHUN AWỌN IBERE TO WA LOJU EWE KẸFA

1 ADO (2) POTOGI (PORTUGUESE)
3 SAMUEL AJAYI CROWTHER
4 DR. MAJẸKODUNMI (5) a) O M I N I R A ILẸ NAIJIRIA (b) NAIJIRIA DI ỌMỌ ẸGBẸ U. N. O.
(d) NAMDI ASIKIWE DI GOMINA AGBA
(6) ỌMỌ EGBE NO 99 (7) KOKORO KOTONKAN
(8) SIR FREDRICK LUGARD (9) Ọ B A FALOLU
(10) NI OSOGUN (11) GHANA (12) VOLTA
(13) ỌDUN 1834 (14) WILLBERFORCE
(15) JANUARY 1st, 1852

Forall your Prrinting Reguirements

Invitations, Programmes, Hand Bills, Pamphlets, Advertising Material and all Commercial Jobbing

Send your Jobs to :-
MODUPE PRINTING PRESS.
16, Bamgbose Street, Lagos. Phone: 21985

Where Quality Print, costs less.

## Obabinrin Gesi ati Phillip Oko re de si Ilu Pakistani



Aworan ti ẹnwo loke yi ni ti Ọbabinrin Gẹsi Queen Elizabeth keji, ati Phillip Ọkọ rẹ ninu ẹwu Ọgagun nigbati Olotu Ijoba ilẹ Pakestani Ọlọla Ayuba Khan nsin wọn sọkalẹ lati inu ọkọ ofurufu ni ibẹrẹ irin ajo wọn si orilẹ ede Pakistani.

Nigbati wọn wa ninu Moto ayọkẹlẹ gbogbo, enia ni o nfi tayọtayọ ki wọn ku abọ.

EYI NI TI EMI...

THREE THREE'S TRIKOLA!




Wa igbadun fun ara rẹ pelu ziru ti o le yọtọmi ti Trikola Didun wiwo rẹ si dara ni gba gbogbo.... o si jẹ oti gbajumọ fun orisirisi eye.

SWORD BRAND

TRIKOLA 333

- LK -

